# IDAJỌ ODODO ỌLỌRUN

**Romu 1:18-25, 28-32; 2:1-16**

**ẸKỌ 381 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitori ojusaju enia kò si lọdọ Ọlọrun" (Romu 2:11).**

**ALAYE**

**Ailẹbi tabi Ẹbi**

Njẹ a ha ti jẹ ọ niya ri nigba ti iwọ ko jẹbi? Boya ni ile-ẹkọ o rú ofin kan ti iwọ kò mọ tẹlẹ pe o wà, tabi awọn obi rẹ ba ọ wi fun ohun ti arabinrin tabi arakunrin rẹ ṣe. Awọn eniyan alailẹbi a maa jiya nigba pupọ, nigba ti ẹni kan ba n jiya, nitori pe o ṣe aitọ ni. Awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ti wọn ti dagba to ẹni ti o mọ rere yatọ si buburu kò le sọ pe, "Emi kò mọ igba ti mo ba n ṣe ohun ti kò tọ́."

Bibeli kọ́ wa pe lati igba ti a ti da aye, ni eniyan ti n mọ̀ọ́mọ̀ dẹ́ṣẹ. Nigba ti Adamu ati Efa mú eso ti a ti kọ̀ fun wọn lati jẹ ninu Ọgba Edẹni, wọn mọ̀ pe awọn n ṣe ohun ti kò tọ, bi o tilẹ jẹ pe wọn n gbiyanju lati ṣe awawi fun aigbọran wọn. Efa wi pe, "Ejò li o tàn mi" (Gẹnẹsisi 3:13). Adamu wi pe, "Obinrin ti iwọ fi pẹlu mi, on li o fun mi ninu eso igi na, emi si jẹ." Ṣugbọn ki ni Ọlọrun ti sọ? Oun ti wi pe, "Iwọ kò gbọdọ" (Gẹnẹsisi 2:17).

**Ohùn Ẹri-ọkàn**

Ọlọrun ti fi ohùn ti a n pe ni ohùn ẹri-ọkan sinu olukuluku eniyan. Eyi jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ọ̀na Ọlọrun n gba sọrọ ninu eniyan lati jẹ ki o mọ̀ ohun ti o tọ́ ati eyi ti kò tọ́. Bi a ba ṣe aika "ohùn" yii si, yoo maa dinku, bi awọn eniyan ba si ti n sé ọkàn wọn le, ki yoo tun fi igba gbogbo maa sọrọ mọ́. Iwa mi-mọọmọ ṣe lodi si ifẹ Ọlọrun a maa pa ẹri-ọkàn mọlẹ. A ni lati ṣọra gidigidi lati feti si ohùn naa.

O ha jẹ pe eniyan ni lati kọkọ mọ Ofin Mẹwaa ki o to le mọ pe ko tọ́ lati jale, tabi pe ko tọ́ lati purọ, tabi pe ko tọ́ lati korira? Lati igba ti aye ti wà ni ẹri-ọkàn eniyan ti n kọ́ ọ lati mọ ohun ti o tọ́ yatọ si eyi ti ko tọ. Ọkàn eniyan kún fun "ẹ̀tan" o si "buru jayi" (Jeremiah 17:9), ṣugbọn eyi ki i ṣe ẹri-ọkàn, afi bi o ba ti séle tabi ki o ti di alailagbara nitori aifeti si ohùn Ọlọrun. Awọn Keferi ni ọna jijin rére paapaa ni ẹri-ọkàn ti o n dá wọn lẹbi nigba ti wọn ba dẹṣẹ. Ko si ẹni ti o le wá siwaju Ọlọrun ni Ọjọ Idajọ ki o si wi pe oun ko mọ ohun ti o tọ́ yatọ si eyi ti ko tọ́ nitori pe oun kò ni Bibeli tabi nitori pe ajihinrere kan ko wa waasu fun oun. Ọrọ Ọlọrun kọ wa pe, "Nwọn . . . . wà li airiwi" (Romu 1:20). "Ọkan wọn si njẹ wọn lẹri, ti iro wọn lãrin ara wọn si n fi wọn sùn tabi ti o ngbè wọn" (Romu 2:15).

**Isin Eke**

Paulu ṣe afiyesi awọn eniyan kan ni akoko rẹ̀ o si wi pe wọn n pe ara wọn ni ọlọgbọn, ṣugbọn wọn di aṣiwere. O wi pe awọn miiran n bọ ẹda ju Ẹlẹda lọ. Wọn ti "pa ogo Ọlọrun ti ki idibajẹ dà, si aworan ere enia ti idibajẹ". Boya bi Paulu ti o kọ ori-iwe yii o ranti ọjọ ti o duro lori Oke Areopagu ti o si kiyesi awọn eniyan naa ninu ẹsin eke wọn. O wi fun wọn eniyan Ateni ki wọn má ṣe ro pe iwa-Ọlọrun dabi "wura, tabi fadaka, tabi okuta, ti a fi ọgbọ́n ati ihumọ enia ṣe li ọnà" (Iṣe Awọn Apọsteli 17:29).

Ṣugbọn iwọ le wi pe, awa n gbe ile ọlaju nihin, a ko sin ẹyẹ, ẹranko, ohun ti n rako tabi aworan ohun kan. Ikilọ kan ni eyi, sibẹ, nitori pe ọ̀pọlọpọ eniyan ni ko sin Ọlọrun lode oni. Paulu n sọ nipa awọn ti o mọ Ọlọrun ṣugbọn wọn ko yin In logo, bẹẹ ni wọn ko si dupẹ, a si mu ọkàn omugọ wọn ṣokunkun.

**Ọlọrun Kọ̀ Wọn Silẹ**

A ka ninu Romu 1:24 pe, "Ọlọrun. . . . fi wọn silẹ": a tun un sọ lẹkan si i ninu ẹsẹ 26; "Ọlọrun ṣe fi wọn fun"; lẹẹkan si i ninu ẹsẹ 28; "Ọlọrun fi wọn fun." Ṣora! Gẹgẹ bi a ti sọ ninu awọn ẹkọ ti o ti kọja, ẹ̀ṣẹ kan a maa fa ọpọlọpọ wá si i. Lakọkọ, wọn kọ Ọlọrun silẹ, nigba naa lẹyin eyi, Ọlọrun kọ̀ wọ́n silẹ. Bi o ba n ṣe faaji ninu ẹ̀ṣẹ, ti o si mọ pe ẹ̀ṣẹ ni, ti o si wà ninu ẹ̀ṣẹ sibẹ, nikẹyin Ọlọrun yoo fi ọ silẹ. O le jẹ́ ki ọkàn were rẹ ṣokunkun.

**Awọn Ẹṣẹ ti "O Yẹ Si Iku"**

Bẹrẹ lati Romu 1:29, a ri bi a ti to ẹ̀ṣẹ lẹsẹẹsẹ -- awọn miiran le dabi ẹni pe wọn tobi awọn miiran si dabi ẹni pe wọn kere. Ṣugbọn ko si awọn ẹ̀ṣẹ ti o kere niwaju Ọlọrun. Ninu akọsilẹ yii ni ẹ̀ṣẹ ti o tobi ju lọ wà, gẹgẹ bi ipaniyan. Ṣugbọn ẹ jẹ ki a wo awọn ti o kù ti a kọ silẹ ninu akojọpọ yii "Asọrọ ẹni lẹhin, . . . . aṣaigbọran si obi, . .,. . . . . . alailãnu." Ẹsẹ ti o o kẹyin ninu ori iwe yii n sọ fun wa pe "ẹniti o ba ṣe irú nkan wọnyi, o yẹ si kú." Ofin ni ilẹ wa wi pe ki a pa ẹni ti o ba paniyan, ṣugbọn Ọlọrun fi idajọ ikú ayeraye le ori asọrọ-ẹni lẹyin, alaigbọràn, ati alailaanu, afi bi wọn ba ronupiwada.

Yoo dara bi a ba ṣaṣaro lori awọn ẹ̀ṣẹ "ti kò tobi" wọnni fun igba diẹ. "Asọrọ-ẹni lẹhin" ni ẹni ti o n sọrọ eniyan lẹyin ni buburu, pẹlu ero lati ba a jẹ́ tabi lati ba orukọ rẹ̀ jẹ́. "Iwọ fi ẹnu rẹ fun buburu, ati ahọn rẹ npete ẹ̀tan. Iwọ joko, iwọ si sọ̀rọ si arakọnrin rẹ: iwọ mba orukọ ọmọ iya rẹ jẹ" (Orin Dafidi 50:19, 20). "Ẹniti o tun ọran hú silẹ, o yà ọrẹ́ nipa" (Owe 17:9). "Asọrọkẹlẹ yà awọn ọrẹ̀ ni ipa" (Owe 16:28). Ẹ má ṣe jẹ ki a jẹbi awọn ẹ̀ṣẹ wọnyii. "Ẹnikẹni ti o ba ru ẹbọ iyìn, o yin mi logo: ati ẹniti o ba mu ọ̀na ọ̀rọ rẹ̀ tọ li emi o fi igbala Ọlọrun hàn fun" (Orin Dafidi 50:23).

**Ni Ikẹyin Ọjọ**

Ọ̀kan ninu awọn ami ti o n fi hàn pe igba ti a wà yii jẹ igba ikẹyin ọjọ ni aigbọran si obi (2 Timoteu 3:1, 2). Eyi jẹ ọ̀kan ninu awọn nnkan ti akọ silẹ pe o "yẹ si iku", eyi ni ni ikú ti ẹmi.

Lode oni awọn eniyan n lo ọpọlọpọ wakati lati wo aworan irira ninu tẹlifiṣọn. Awọn iwe apanilẹrin ati awọn iwe itan arokọ ni awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin n kà dipo eyi ti wọn i bá fi maa ka Bibeli wọn. Boya awọn ti n ṣe iru nnkan bawọnni ni Ọrọ Ọlọrun sọ nipa nigba ti o wi pe: "Ati gẹgẹ bi nwọn ti kọ̀ lati ni iro Ọlọrun ni imọ wọn, Ọlọrun fi wọn fun iye rira" (Romu 1:28). Ohun ti "iyè rira" duro fun ni "kikún fun iwa ẹ̀ṣẹ ni gbogbo ọna." Ọlọrun fi wọn silẹ. Ẹni kan ti sọ pe, "Iwe ti o ba kà ni iwọ yoo hù ni iwa." Ki ni iwe ti iwọ n kà?

**Ọjọ Idajọ**

Ọlọrun ki i ṣe ojusaju eniyan. Lọjọ kan Onidajọ ododo "yio san an fun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀." Ẹṣẹ n ṣe akójọ tabi "o nfi ibinu ṣura" fun ara rẹ̀ de Ọjọ Idajọ. Ṣugbọn iye ainipẹkun, "ogo, ati ọlá, ati alafia wà fun olukuluku ẹni ti nhuwa rere." Ki ni ireti rẹ "li ọjọ na nigbati Ọlọrun yio ti ipa Jesu Kristi ṣe idajọ aṣiri enia?" "Ṣugbọn bi awa ba wadi ara wa, a ki yio da wa lẹjọ" (1 Kọrinti 11:31). Bi o ba jẹ ẹlẹṣẹ, má ṣe nireti pe o ṣe e ṣe ki "igbẹhin rere" ṣẹlẹ si ayé rẹ. O ni lati fi Ọrọ Ọlọrun diwọn ayé rẹ wò ki o si mọ̀ ibi ti iwọ iwọ yoo ti lo ayeraye.

Akoko kuru; Jesu n bọwa lai pẹ jọjọ. Olukuluku ẹni ti o ba n fẹ lati fi Ọrun ṣe ile rẹ̀ ni lati wá Oluwa lonii pẹlu ọkàn ti o ṣipaya.

Olooto ni Ọlọrun, "kò fẹ ki ẹnikẹni ki o ṣegbé, bikoṣe ki gbogbo enia ki o wá si ironupiwada. Ṣugbọn ọjọ Oluwa mbọwa bi ole li oru" (1 Peteru 3:9, 10).

**AWỌN IBEERE**

1 Darukọ, o kere tán, ẹ̀ṣẹ mẹwaa ti a wi pe o "yẹ si iku."

2 Ki ni ṣe ti eniyan ko le ri awawi ṣe ti yoo jẹ́ itẹwọgba niwaju Ọlọrun fun didẹṣẹ?

3 Sọ apẹẹrẹ awọn miiran ti wọn gbiyanju lati ṣe awawi fun ẹ̀ṣẹ wọn.

4 Sọ itumọ "ẹ̀ṣẹ."

5 Atunṣe wo ni Ọlọrun ti pese silẹ fun ẹ̀ṣẹ?

6 Ki ni a n pe ni "ohùn ẹri-ọkàn"?

7 Ki ni ṣe ti a ni lati maa feti si ohùn yii?

8 Ijiya wo ni o n duro de awọn ti n ṣe ibi?

9 Ki ni yoo jẹ ère olododo? Yoo ha pé fun eniyan lati jẹ olododo?